# Fatḥ al-Muʿīn Fī Taqrīb Manhaj al-Sālikīn Wa Tawḍīḥ al-Fiqh Fī al-Dīn,
# By Sheikh Haytham Bin Muḥammad Sarḥān (ḥafidhahullah)

(the former teacher of the Masjid of the Prophet ﷺ)

## Idajọ zakaat al-Fitr:

O jẹ ọranyan fun ẹnikẹni ti o ba jẹ Musulumi ti oorun ba wọ balaye ni ọjọ ikẹhin oṣu Ramadan: yala o jẹ agbalagba tabi ọdọ, ọkunrin tabi obinrin, ẹru tabi olominira, ti ounjẹ jaka kan ba ṣẹ́kù ni ọ̀sán àti òru ọjọ ọdun yatọ si oun ti o maa tó fun-un ati ara ile rẹ̀ ati àwọn bukaata rẹ̀ tí ó jẹ tulaasi.

A fẹ ki a yọ fun oyun inu obirin.

**Ọgbọn ati oye ti o wa nibi ṣiṣe Zakat al-Fitr ni ofin:**

- Imọtoto lo jẹ fun alaawẹ̀ kúrò nibi ọ̀rọ̀ isọkusọ ati ọ̀rọ̀ ọ̀ṣì.
- Ọrọ̀ wà ninu ẹ fun awọn alaini ati awọn talaka kuro nibi ima tọrọjẹ ni ọjọ ọdun.

**Asiko ti a maa n yọ zakat al-Fitr:**

| | | |
|---|---|---|
| Asiko tí ó lẹtọọ ki yọ ọ ni ọjọ kan tabi ọjọ meji ṣaaju ọjọ ọdun. | Asiko ti a fẹ́ ki a yọ́ ọ ni ṣaaju irun yidi lẹyin irun asuba. | Èèwọ̀ ni ki a yọ́ ọ lẹyin irun yidi. |

**Awọn nnkan tí ó tó fún zakat al-Fitr:**

Jaka kan ounjẹ tí awọn eniyan n jẹ, odiwọn jaka kan wheat tí ó dara jẹ kilo meji ati ogoji giramu, nitori naa a o maa ṣe isiro gbogbo ounjẹ pẹlu nnkan ti jaka kan bá wọ̀n.

Pínpín owo kò tó lati fi yọ zakat al-fitr.

**Odiwọn ounjẹ zakat al-Fitr ninu awọn ounjẹ tó gbajumọ pẹlu oṣuwọn wọn:**

| | | |
|---|---|---|
| Fulawa: 1400g | Wheat: 2040g | Ẹwa: 2060g |
| Sẹmo: 2000g | Adas: 2100g | Dabinu: 1800g |
| Irẹsi: 2300g | Imas: 2000g | Zabeeb: 1640g |

**Awọn ọna tí zakat pin si latari wiwo olugba ati odiwọn:**

| | | |
|---|---|---|
| [1] Eyi tí a ti pebubu zakah ti a fẹ san lai wo ẹniti o san-an tabi ẹni ti wọn san-an fun, gẹgẹbi zakat al-fitr. | [2] Eyi tí a ti pebubu nnkan tí a fẹ san àti ẹni tí a fẹ san-an fún gẹ́gẹ́ bi ìràpadà ṣuta ṣiṣe:"Fun àwọn tálákà mẹ́fà ní ounjẹ, ọ̀kọ̀ọ̀kan ninu wọn yoo gba idaji jaka". | [3] Eyi tí a ti ṣe adayanri olugba ati olusan-an lai pebubu ohun tí yoo san, gẹ́gẹ́ bi itanran fún ibura. |